# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## ASA OWO KIKỌ NI ILU ISẸYIN

Inu mi yio dun ti Olotu ba le gba mi laye lati sọ ẹdun ọkan awa Onişowo Isẹyin si eti awọn alaşẹ Ijọba lati ba wa pa aşakaşa ti awọn nda nipa owo kikọ,

Ti nwọn ba ri owo ti a ti ngna ti o ti pẹ nwọn a wipe o ti yọ awọn ko gba a, ti o ba si jẹ owo titun ni nwọn a ni bọya owo Ijẹbu tabi owo aiyederu ni nwọn ko ni igba a.

Wahala pupọ ni o wa fun awa onişowo Isẹyin nipa owo kikọ yi nitoribẹ a bẹ awọn Alaşẹ Ijọba lati ba ni şe kilọkilọ fun awọn ti nkọ owo daradara wọnyi pe owo aiyederu nikan ni ki nwọn ma a kọ.

Awọn Alaşẹ Ijọba le ran enia wa si ọja alẹ ni isọ ẹgusi lati wa fi wadi ọrọ nipa ọran yi,

## GERI ALIMI ALMANACK 1952 KOSI

Inu mi yio dun ti Olotu ba le gba mi laye lati sọ tẹlẹ fun awọn onkawe Iroh'n Yoruba ati gbogbo awọn ti o mba mi ra ILỌRIN GERI ALIMI ALMANACK pe ko ni si ALMANACK na fun ỌDUN 1952 nitoripe iwe ti a fi nşe e han pupọ.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi lati şe ifilọ yi fun awọn onibara mi.

Emi ni
J A ARẸẸGBẸ
Aşoju Irohin Yoruba.
P.O. Box 7.
ILỌRIN

A dupẹ o Olotu fun aye ti ẹ gba wa yi.

Emi ni,
Emanuel Alao
ISẸYIN

## AMODI IMU TI LỌ




**MENTHOLATUM**




Ki amodi imu ba le tete lọ, lo "Mentholatum", Pẹlu iyanu ni egbogi fifa-si-imu yi fi tete nyaraşişẹ. Ẹsẹkẹsẹ ti o ba ti lo o ni wa si ri i pe pẹlu irọrun ni gbogbo idọti imu o ti bẹrẹ si jade lẹsẹkẹsẹ. Orun "Mentholatum" a tete fun ẹ ni aye a ti ma a mi dada. Ki o si tun fi pa ọfun ati aiya fẹẹrẹfẹ. Eyi na a si tun ma a mu ki gbogbo iwọjọpọ ailera lọ kiakia. Tete lọ ra idẹ tabi agolo "Mentholatum" kan loni.

Bere fun Mentholatum gan an. Eyiti o jẹ pe awọn Mentholatum Co. Ltd., (Est. 1849) Slough, England nikan ni nwọn nşe e.


# IKEDE IJOBA

APA-BIBU FUN ARUN IBA-PỌNJU PỌNJU ATI ILẸẸ-GBONA FUN AWỌN TI O BA FẸ WỌ ỌKỌ OFURUFU LỌ SI IDALẸ (Yellow Fever and Smallpox Vaccinations and other Inoculations for persons intending to travel by Air.)

Awọn ti o ba fẹ wọ ọkọ ofurufu kuro ni ilẹ yi (Nigeria) lọ si idalẹ ni lati ni Iwe-ẹri apa bibu (Internation Certificates of Vaccination) ti o daju fun ti Iba pọnju-pọnju ati ti Ilẹẹgbona lọwọ

### ARUN IBA PỌNJU-PỌNJU (YELLOW FEVER)

Ti o ba şe pe AKỌKO bu apa fun Iba pọnju-pọnju ni awọn ero Idalẹ na ko gbọdọ ti i kuro ni Nigeria titi ọjọ mẹwa yio fi kọja lẹhin ti nwọn ba ti bu apa tan Awọn ti o ba şope awọn tun bu apa fun ni ekeji ni le ma a lọ lẹhin ti nwọn ba ti bu u tan, ti a ba ti ri ẹri ti o daju han Bupabupa (Inoculating Officer) na pe akoko ti nwọn ti bu ti akọkọ ko ti kọja ọdun mẹrin ni o, ki o si tẹ e lọrun pe Iwe ẹri atunbu-apa ni gan an.

Ni ibi pataki ni a le fi aye apa bibu fun Iba pọnjupọnju yi si, ki o le din iyọnu a nwọkọ kakiri ku ati ki awọn ohun elo rẹ le bọ si arọwọto, ki işẹ paapa sile rọrun ni şişe.

Ibi ti aye apa-bibu na wa ni :— Eko, Kano, Zaria, Jos, Kaduna, Yola, Maiduguri, Şokoto, Gusau, Ilọrin. Minna, Ibadan Port Harcourt, Enugu, Warri, Calabar, Forcados, Victoria.

Apa bibu (Yellow Fever Inoculations) ti awọn enia ti o ba wa ni Eko yio jẹ lati ọdọ Pathology Department Broad Street, Lagos, ni agogo mẹsan Araro Satide. Awọn ti o si le ri aye apa bibu na ni awọn ti o ba ti şe eto rẹ tẹlẹ pelu Pathologist Lagos nipa iwe kikọ tabi ki o tẹlifonu (Tel, Lagos 332) o pẹ patapata ni ọjọ kan (24hours) şaju akoko ibupa na,

### ILẸẸGBONA (SMALLPOX)

A ni lati duro fun ọsẹ kan lẹhin Ibupa Ilẹẹgbona ki a to jade gẹgẹ bi eto si apa keji Iwe ẹri Apa-bibu (Internation Certificate) pe Bupa-bupa (Vaccinating Officer) na n lati yẹ ibiti a gbe şe ibupa na wo ni ọjọ karun titi di ọjọ keje lẹhin ibupa na. Akoko ti Iwe-ẹri (Certificate) na wa fun ko kọja ọdun mẹta si akoko ti a kọ ọ.

Ti o ba şe pe nipa ti Apa-titun-bu ni, ero idalẹ na ni lati wa sọ fun Bupa-bupa (Vaccinating Officer) na ni ọjọ keji ti o ba ti bupa na.

Ni Health Office, Broad Street Lagos ni awọn ti o ba wa ni Eko ni lati ma a wa fun apa-bibu ti wọn ni arin agogo mejọ arọ ati agogo mejila ọsan lojojumọ (afi ọjọ ọsẹ nikan) ati ni Port Health Office, Lagos, ni arin agogo mẹjọ arọ ati agogo mẹwa ni ojojumọ (afi ọjọ ọsẹ nikan).

### APA-BIBU FUN ARUN MIRAN

Ni ti apa-bibu fun arun Onigbameji (Chollera) Akọ-iba (Typrhus) ati Ajakalẹarun (Plague) a ni lati lọ bere lọwọ Patgologist i/c Pathology Department, Lagos (Tel. Lagos 332) tabi ki o kọwe si eyikeyi ninu awọn Senior Medical Officer.

**Director Of Medical Services.**


# J. A. Ajao & Brothers

GENERAL MERCHANTS
10, Egerton Road, Lagos, Nigeria

A nta awọn nkan wọnyi:— Işana orişirişi (Matches), Oogun Iyagbẹ, (Epsom Salt), Kafura Pẹlẹbẹ (Camphor), Atike (Face Powder), Ọti Didun (Mineral Water), Cement, Bata Funfun (White Canvas Shoes Leather Shoes (orişirişi), Beer, Shnapps. Gin, Wine, Brandy.

## Medicine Stores

A tun nta awọn orişirişi ògun ni oke Şọbu wa — Oogun Narun Iba, Atun-ẹjẹ-şe, Ikọ, Jẹdi-jẹdi, ati ògun fun Obinrin ati Ọkunrin Lakuregbe, Ehin Ọmọde.

ẸMÁA KA IWE **Irohin Yoruba** NIGBA-GBOGBO

